# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 850 LAGOS SATURDAY DECEMBER 22 — I ICEMEFI 28 1962 K Ọ MEI (CD)


# Oloye Akintola Yio Pada Si Ibadan Laisi Tabitabi

IBADAN—Pẹlu ariya ati ayọ ni gbogbo awọb ara Iba dan fi npalẹmọ ni igun merẹrin ilu na lati gba Oloye S. L. Akintọla ni alejo pada si ori aga Ijoba Iwọ Orun ti Oloye Akintọla ti fi igba kan ṣe Olotu rẹ ri ki rogbodiyan awọn ọmọ Ẹgbẹ Action Group to bẹ silẹ ni iwọn oṣu kẹfa sẹhin.

Rogbodiyan na si ti sọ ọpọlọpọ enia di isansa ati alarinkiri, bẹni awọnmiran si ninu kilakilo rogbodiyana.

A gbọ wipe eto ti nto ati pe awọe Igbimọ ti fidara mọ wipe ki Oloye Akintọla pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ UPP ma ba iṣe Ijọba ipinlẹ na lọ.

Laisi aniani, Oloye Akintola yio pada sori aga ni oṣu yi (December) to de ilẹ. Ki eku ile sọ fun toko.

## Alhaji Ggadamosi Apatira Jebi Anotu

Laipẹ yi ni adajọ Agba D. Onyeama da Anọtu Apatira lare ẹjọ lori kotẹmilọrun ti o pe Alhadji Gbadamọsi Apatira o si ni ki o lọ san pọnun mọkanla ati ṣile mọkanla (£11 11s owo irin-ẹsẹ fun obinrin na.

Bi ẹjọ na ti ṣe lọ si ni pe Alhadji Gbadamọsi lo kọkọ pe Anọtu Apatira lejọ siwaju adajọ kotu kekere kan l'Eko. O ni Anọtu ko ni ẹtọ rara lati lọ lo iyara kan ni 9, Apatira Street, o ni si ti gboju-gbaive lọ ko ẹru rẹ sibẹ. Adajọ na si da Alhadji Gbadamọsi lare.

Anọtu Apatira ni idajọ na ko tẹ on lọrun rara ni o ba pe ẹjọ kotẹmilọrun" (Appeal siwaju Adajọ agba Ọgbẹni Onyema, o si da a lare.

Idi ti o fi da a lare ni pe, kotu-kekere ko ni ẹtọ ati agbara lati da ẹjọ lori tani ni ile tani ko ni ile na.

Ninu ẹjọ ti Anọtu ro, o o sọ wipe Alhadji ki iṣe ọmọ baba on ti o njẹ

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## OFIN PAJAWIRI PIN LOSE TI MBO

EKO— Olotu Ijọba Apapọse, Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa ti kede nkan ti o berẹ ni oru ọjọ kọkanla loni (ọjọ Aje) tiṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu yi, ofin pajawiri ti nwọn ti fi de Ijọba Iplnlẹ Iwọ Orun mọlẹ yio kasẹ nilẹ olukuluku awọn aṣoju ti nwọn yan si ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ na a si pada si aye wọn.

Ọlọla Tafawa Balewa ni o nsọrọ yi fun awọn oniwe ohin ni gbara ti o ti gunlẹ ni Ikẹja nigbati o nti Fortamry iblti nwọn gbe lọ ṣe ipade pataki kan bọ. O ni on Lo tun gbe aṣeyọri ọrọ ẹnkuari (iwadi) ti Adajọ Coker ṣe jade ki a to ṣe ọdun Keresimesi, boya ni ọtunla.

Onirohin wa ni agbegbe Ọshun tẹ waya si wa ni alẹ ana wipe Alhaji D.S. Adegbenro, Ẹkẹrin Ẹgbẹ, ti fi ofin pajawiri fi si ihamọ ni Oshogbo paapa ti npalẹmọ lati iọ ọdun titun ninu ile rẹ ni Agọ Owu ni Abẹokuta.


## LAGOS RACE CLUB

FIRST DAY
Christmas Race Meeting
TODAY
First Race at 3. 30 P. m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2.10/-, 2nd £1.10/- and 3rd 10/-.

**Come One Come All.**

Hon, Secretary,
Lagos Race Club.


## Owo Ilewe Di Gbefe Fun Mekunnu

IBADAN—Ire wọle de! Irohin ti o tẹ wa lọwọ loru ana ni ti owo ile-iwe giga ti awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun sọ wibe awọn yio dinku ki awọn ọmọ mẹkunnu le ni anfani lati kọ ẹkọ wọn siwaju si. Nwọn ṣe ikede yi lori iwadi kan ti Nwọn ni ki Ọgbẹni Ajayi pẹlu awọn kan ki nwọn wa lori owo ilewe ti awọn tiṣa kan bu le awọn obi lori ni ibukubu.

Nwọn tun ṣe alaye ninu ikede Ijọba na pe gbogbo awọn tiṣa ti nwọn ba ṣẹṣẹ nkọ'ṣẹ ko ni san owo-ẹkọ wọn mọ a fi owo onjẹ wọn nikan, iyẹn ko si ni ju pọnun mẹjilelogun titi de ọgbọn pọnun lọ fun awọn tiṣa ti o ba fẹ pari ẹkọ wọn.

BI OMODE BA KOYAN ALE.....

# Oloye Ojikutu Pa Itan Awon Alapata

Gegebi Oloye Abadu Yetunni Ojikutu ti so fun iwe irohin Eleti-Ofe ti o koja wipe şaşa ni awọn ti o npe ara wọn ni alapata ẹran lode Eko nisisiyi ti o le sọ itan on, ati pe itan ti Ọgbẹni Madojutola pa wipe nigbati o n Oloye Ojikutu wa ni ilewe ni awọn ti da ẹgbẹ Alapata ẹran silẹ, itan alaimọkan ni nitoripe odo ti a mo orisun rẹ ki i gbe ni lọ ni gbogbo itan ti o pa na nipa Olori ẹgbẹ wọn yi.

## Oba Agba

Oloye Ojikutu ni awọn agbalagba ti on ba lẹnu işẹ apata ẹran ti on juba ni awọn bi Alagba Ologbe Sunmọnu Ayilara, Sunmọnu Adeleke, Atanda Baba Abinde ni ita Tinubu. Adetunji Aminu (aburo Ayilara), Abu Bakare ọmọ Ekunsumi, Amọdu Rufayi Ọlọrunkoje, Bello Latẹju, Bello Sulọla, Adubiaran, Mọnmọ Olunlade (ti Ijaiye) ati awọn alagba kan ti awọn ma npe ni ẹlẹran-ẹgbẹ nigbana, awọn bi Lala, Mọnmọ Dangojemu, Ibrahim Tembere, Dan Meriya ati awọn bẹẹbẹ. Ninu gbogbo wọn yi alagba Mọnmọ Olunlade nikan loku lori ilẹ loni.

## Itan De!

Oloye Ojikutu ni, "Ninu awọn agbalagba obinrin ti o tun le sọ itan bi mo tise bẹrẹ işẹ apata ẹran, ọpọlọpọ ni o ti jalaisi ninu wọn a fi agbalagba Shinyanbọla ti o wa lori ilẹ loni.

"Nwọn ni bi ọmọde ba kọ iyan alẹ, agba a fi itan ba'lẹ, Mo fẹ wa fi abọ ọrọ mi s'ori awọn ti nwọn ni awọn mọ itan bi mo ti şe di alapata ẹran.

"Ekinni, fun ọdun gbọọrọ, işẹ lebira ati alagbata ẹran ni Ọgbẹni LAWANI MADOJUTỌLA nşe lọdọ Jẹminatu Ọlọka ti o ngbe agbole Abijọ ni ita Tinubu. Lẹhinti Jẹminatu jalaisi ti mo di Olori alapata ni Madojutọla na bẹrẹsi pa ẹran nigbati emi pẹlu awọn agbalagba ẹgbẹ alapata ita Faji fẹnu si i lọdọ dokita ti o wa fun imototo ilu Eko, ni nwọn fi fun unni isọ kan.

"Ẹnikeji ni Ọgbẹni Popo Ọnayẹmi, on paapa işẹ ọmọ-ọdọ ati alagbata ni ai o nşe ọdọ Raliatu Ojikutu titi ni ọja Ereko ki Bukọla, ẹgbọn rẹ to mu u wa si ọdọ Bello Latẹju ni ita Faji pe ki o ma baa kun ẹran. Ni ọdun kẹta ti ogun bẹrẹ, o bẹrẹsi ta 'bure' ki o to di ẹniti o npa ẹran laipẹ yi.

"RAJI ADEYẸMỌ ni ti ẹ, ọmọ işẹ a kiri ẹran ati a-şa-egun ẹran ni o nşe labẹ Sadatu Aunti Ọffa fun ọdun gbọọrọ ki o to wa bẹrẹ ẹran ni pipa labẹ Olori wọn, Oloye Ojikutu lẹhinti Aunti Ọffa ku.

"Raji ti a npe ni Alhaji Raji nisisiyi jẹ ọmọşẹ aşa egun ati akiri ẹran labẹ Hunmani Iya Lamidi. Lẹhin iku iya yi, o wa di ẹniti o npa ẹran labẹ Olori wọn kanna yi ti o nko gbogbo wọn jẹ.

(wo yoku loju ewe kẹjọ)

AWỌN OLOTU ATI OŞIŞẸ ILE IŞẸ

J. T. CHANRAI & CO. (NIG.) LTD.

FI TỌKAN TỌKAN KI ẸNYIN ONIBARA WỌN JAKE JADO NIGERIA PE

E KU ODUN KERESIMESI

Ẹ SI KU IPALẸMỌ

ODUN TITUN TI MBO; ODUN NA YIO YA'BO.

44 MARINA LAGOS. | 39 LEBANON ST. IBADAN. | 12-S LIVERPOOL RD. KANO.



## ADAJỌ NI KI MEYỌ ANA FI ILE FUN ONILE

EKO— Owo ko ni iran, ko si ẹniti owo ko le da, iyẹn ni ọrọ ti Dokita Ibiyinka Ọlọrunnimbẹ, ti o kọ jẹ oye Meyọ (Mayor) ni ilu Eko ti adajọ-agba awọn Kotu Ọlọpa paşẹ fun ni ijẹrin wipe ko fi ile onile silẹ nitori gbese ti o jẹ onile.

Iya onile, Iya'fin Ronkẹ Lucas (ọmọ ologbe Dokita Adefolu) ni o gbe Dokita Ọlọrunnimbẹ si iwaju adajọ Ọgbẹni Bakare wipe ile ti o ngbe ni 8, Turton Street l'Eko ko san owo "mehaya" oşoşu fun on lati ọjọ gbọrọ; gbogbo owo ti o ha s'ọrun dokita na nlọ bi pọnun mẹrinlelọgọrin, sile mẹrindinlogun ati sisi (£84 16/6d) on si bi ni gbese na titi ko su jaa.

Nigbati nwọn ro ọrọ na titi, adajọ kotu ni on fun Dokita Ọlọrunnimbẹ ni aye oşu mẹta gbako ki o fi ko ẹru rẹ kuro ninu ile na ati pe ki o san pọnun mọkanlelogun (£21) owo irin ẹsẹ fun iya onile rẹ t o wọ wa si kotu.

# Eja-Lo-Ni–Bu





LONDON—Bi akoko yi ti jẹ akoko otutu to ni ilu Oyinbọ awọn ọmọ ilu Gẹsi ko e fi wiwẹ lodo ṣere nitoripe nwọn kan si nkan iṣere pataki, nwọn si tun ni aṣọ ti nwọn ma nwọ ti nwọn ba fẹ lọ wẹ iwẹ yi lodo.

Ninu awọn aworan ti o wa loke yi ni ẹ o ri awọn meji kan ti nwọn gba ẹbun ri bi lori ere–iwẹ ni ilu Oyibo na ati ọd mọbinrin kan, Margeret Austen, ti o ngbadun aiye rẹ lẹhinti o ti wẹ tan.

# Itan Ijapa Ati Ojola

## (Lati Owo Babalorisa)

Ni igba lailai ti aiye wa ni oju ekun, ijapa ati ojola nwọn a ma ṣe ọrẹ pọ. Ọrẹ nwọn na dun pupọ tobẹgẹ ti nwọn o nfi nkan pamọ fun ara wọn. Nwọn si ma nba ara wọn jẹun.

Bi ẹnikẹni ninu nwọn ba fẹ lati jẹun ti ko si ri ẹnikeji rẹ ko ni jẹ onjẹ na; bi ẹnikan ninu ọrẹ mejeji na ba ni ọrọ asiri, o ni lati sọ ọ fun ẹnikeji rẹ.

## Aiperi De

Nwọn ṣe eleyi fun ọdun pipẹ, ọrẹ nwọn na si ndun yungba yun ba ki aiperi to ta wọọ.

Nigbati o di ọjọ kan ni ojola bẹ ẹsi ro o lekun ara rẹ wipe lawo ti on yio ti ṣe e ti ọrẹ on ajapa yi ko ni ba on jẹ onjẹ mọ nitoripe onjẹ ti on le dun pupọ ju ti ọrẹ on ajapa yi lọ.

O ni gere ti iyawo on ba ti se onjẹ tan, ti o gbee ka'lẹ ri on yo ti fi ara on yi awo onjẹ na ka ki on to ranṣẹ si ajapa ninu ile rẹ pe ki o wa jẹun. Ojola jẹ nkan ti ẹlẹda da ti o gun, nitori eyi o ni anfani lati ka ko yi awo-onjẹ ka dara ara.

## Awada Ni ?

Ni ojọ kan ti iyawo rẹ se adidun onjẹ kan tan, ti o gbe kalẹ, Ojola ni lon ni on yio fi iwa kilọ fun ọrẹ on ajapa wipe on ko fẹ ki o ba on jẹ onjẹ mọ rara, ni o ba ka ara rẹ yi awo-onjẹ na ka. O ni ki nwọn ba on pe Ajapa ki o wa jẹun.

Lati ẹnu ọna ile na ni onjẹ na ti nta sansan si imu Ajapa, ebi tilẹ wa lara rẹ lọjọ na. Bi o ti wole o ri ti ọrẹ rẹ Ojola ti fi ara rẹ yi awo-onjẹ ka. Awada ni o pe ọrọ na ni akoko, ṣugbọn nigbati o sunmọ awo-onjẹ ti o ni ki on na ẹnu si i ẹsẹ rẹ tẹ ara Ojola mọ'lẹ. Ojola ni Ajapa mọ pe ọ ki o wa jẹ onjẹ nṣe ni o si ntẹ mi mọ'lẹ.

Ajapa tun yi si ibomiran bakanna ni o tun tẹ Ojola mọlẹ, ti Ojola si tun sọ bakanna fun un pe on le wipe ki o wa ba on jẹun ki o ma tẹ on mọlẹ bayi

Eleyi jẹ ki Ajapa papa mọ wipe Ojola ko fẹ ki on ba on jẹun mọ, ni o ba pa la sinu ile rẹ.

(We yoku loju ewe kẹfa)

## Eleti–Ofe D'araba

# ELETI—OFE

ANJUWON KO ŞE WI LEJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELEGRAM
28 Kosoko Street, Lagos. "E. ETI—OFE" LAGOS
P. O. Box 468 Phone 23370

VOL XIV No 849, SATURDAY, DEC. 15, - DEC. 21, 1962


# Keresimesi Odun De 1)

O bere lati ojo oni lo, opolopo oke aimoye enia ni nwon a ma yo lori omo kan ti nwon bi nigba kan, ni ilu kan ti nwon n p e ni Betilehemu ti nwon si so oruko re ni Jesu Kristi A gbo wipe on ni o ni lati se olugbala awon ara aiye.

Gegebi akosile irohin ti a gbo ninu iwe Bibeli nipa omo na awon obi omo na ki i se Olowo rara, nwon ko si ni aso - aran lati te sile nigbati nwon bi i. Ninu ile ti awon ewure ati aguntan nsun ni nwon bi i si.

## B'A–Ti-B'ERU

Enikeni ti o ba so wipe omo olokiki ni o m o na yio da lehinwa ola (iyen lojo oni) Oluwarẹ npuro ni.

Jesu Krisiti j e abami omo nigbati nwon bi, ti o fi je wipe awon "amoye" meta kan dide ni ilu won lati lo ba awon obi re y o avo nla nigbati nwon bi i nitoripe nwon ri ninu irawo (atesebi) se pe o m o y i w a s'aiye fun nkankan pataki ni.

## LA B'OMO

Irin ti awon baba amoye meteta na rin lojo na ko kere rara. Irin ajo won na n i o dabi irin a j o awon enia mimo kan (Prigrim's Progress) ti a le fi we ni ojo oni.

Opolopo omo ni a mbi lojo oni ti enikeni ko le mo nkan ti nwon a da lehinwa ola. Omiran nwon bii sinu ahere oko ti nwon ti lo se'gi igbago, omiran nibiti iya re ti nse ise alajapa kakiri.

Nwon ni kosi orile-ede kan ti ko ni ni "WOLI" tire, sugbon a kii tete m o nwon, a fi lehinti nwon ba se ise won tan ti nwon ti lo.

**Awa Oniwe irohin Eleti-Ofe ki enyin okawe wa jake jado Nigeria, Ghana ati Dahomey wipe e ku odun, e ku iyedun. Ajinde ara–yio ma je fun gbogbo wa.**

——OLOTU

# Iwe Si Olotu

## ETUN WA KA

Inu wa dun pupo lati gbo wipe awon olotu Ijoba wa ngb'ero lati tun enia ka kakiri gbogbo ile Nigeria nitoripe eyi ti nwon ka ninu osu keje l o h un ko pe rara.

Nitoto, ko pe, nitoripe emi ati awon enia mi ko fi oju kan awon akowe akania nigbati nwon so wipe nwon nka wa na. Mo si tun mo opolopo awon enia ti nwon ko ri ka ni agbegbe odo wa.

Bi nwon ba tun le t u n gbogbo wa ka ni i p i n l e Ijoba Iwo Orun, Ila Orun ati Ariwa a dara pupo ju nitoripe a ko oro a-ko-ka-mo ikan lodo wa ni Ipinle Iwo Oru.

Mo dupe lowo yin fun aye ti e gba fun mi ninu iwe irohin yi.

Emi ni.
Otta Omode


**HAVE YOU exchanged your OLD WEST AFRICAN COINS for Nigerian Money ?**

FREE EXCHANGE at banks ends or **December 31st, 1962**



## THE ELETI – OFE

28, Kosoko Street Lagos.
P. O. BOX 467. PHONE 23370

This is to inform our advertisers and agents that the following new scale of advertisement rates will be charged by this Paper from 1st January 1963.

### SCALE OF ADVERTISEMENT RATES
### DISPLAY ADVERTISEMENTS

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| Full Page | £40 | 0s | 0d | per insertion |
| Half Page | £25 | 10s | 0d | " " |
| Quarter Page | £15 | 0s | 0d | " " |
| 1–12 Insertions | | 15s | | " " |
| 13–25 Insertions | £ | 12s | 6d | per single col. inch |
| 26–52 Insertions | | 10s | | " " |
| Front Page | | 15s | 0d | " " |
| Leader Page | | 10s | 6d | " " |

Special position 50 per cent additional

### CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| Legal Notice—— | £0 | 15s | 6d | per insertion and |
| Change of Name | £0 | 15s | 6d | not exceeding |
| Thanks for Sympathy | | 15s | 6d | 40 words |
| In Memoriam | £0 | 15s | 6d | |

### CONDITIONS

All advertisement orders intended for publication must reach this Office not later than Wednesday of every week preceeding the date of Publication.

Advertisement rates are liable to alteration but sufficient notice will be given to our advertising agents

Classified advertisements will be set in suitable types at our discretion. We reserve the right to edit any or reject advertisement submitted to us for publication if it is considered that such advertisements are against our editorial Policy or the Laws of Nigeria.

By Order
ADVERTISEMENT MANAGER.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI OWO AYILUKA)

## Omo Ni Wura

Keresimesi, ọdun de! Ninu ọjọ diẹ ti ọdun na fẹ de ba wa yi Olodumare, jọwọ gbọ ẹbẹ wa, maṣe jẹki a padanu ẹmi ninu rẹ. Adura emi Ayiluka "Eleti-Ọfe" ni pe ẹniti ko ti ri ọmọ bi, ko fi ẹhin re pọn ọmọ ninu ọdun ti a fẹ bọ si yi. Ni ilẹ awa Yoruba, ọ m ọ ni Wura, ọmọ ni jingi, ti a fẹran lati ma ji wọ nigbagbogbo. Olodumare na ki o maṣe fi awọn ọmọ ti o bi fun wa na la wa loju ki a to jade ninu aiye.

## Olorun Eko

Ẹnyin ọkawe mi, Ọlọrun ilu Eko ko le rara a fi awa enia ibẹ ti a roro. Mo g b ọ irohin wipe ọrẹ mi atijọ, Ọgbẹni Kofie Blankson ti tun gba ipo si ipo rẹ; nwọn ti yan ni alaga ile iṣẹ tuntun ti nwọn npe ni Nigerian External Telecommunication Ltd., ile iṣẹ waya okere ti ijọba Apapọṣe ṣẹṣẹ gba l ọ w ọ awọn Oyinbo ti o ti nṣe e ri.

O to ọdun mẹrinlelogun nisisiyi ti m o ti m ọ Ọgbẹni Blankson nigbati gbogbo wa jọ nwa "igboje" kiri ni ile itẹwe Zik's Press ni Market Street l'Ẹhingbẹti l'Eko. Ọga ni Ọgbẹni na jẹ fun mi pelu Ọgbẹni Shomolu (adajọ – agba ni Ibadan nisisiyi) ati awọn Ọgbẹni J.C. Okwesa, Mobọlaji Ọdunewu (on nṣe ọga ni ile ikede Ijọba nisisiyi), M R.B. Ọttun pẹlu Ologbe B B Salami. Baba'salẹ wa nigbana ni Ọlọla Nnamdi Azikiwe, Gomina-agba.

## Ko Buru

Ọlọla Azikiwe na ni Ọgbẹni Blankson ba wa si ilẹ yi lati Ghana (Gold Cost ni a npe ilu Aganyin yi nigbana), on na ni o si kọ ran an lọ si Pọta (Port–Harcourt) nigbati a lọ da iwe irohin ti npe ni "EASTERN GUARDIAN" silẹ ni 1940.

Ọgbẹni Blankson, ki ẹ niran awa na o, Ọlọrun ilu Eko ko roro ti ilu Aganyin paapa ko buru, awa ọmọ araiye lẹbọ.

## Banki Larubawa

Nwọn ni ewo mbẹ lẹsẹ odo! Banki Larubawa ti nwọn npe ni Arab Bank paapa ti wa fidi sọle si ọdọ wa ni Nigeria. Nwọn ṣi ẹka banki na kan si Eko ni ỌjọRu ijẹrin. Oloye Festus Okotie – Ebo tiṣe minisita alamojuto eto owo apapọ Ijọba ilẹ Nigeria ni o ba wọn ṣi ile ifowo pamọ na ni io ti gbogbo wa ti mọ ni Porto Novo Market Street ri, ti a si sọ ni Abibu Oki Street.

Mo gbọ wipe ile ifowo pamọ si na ko d i ẹ ni ilu awọn Musulumi ati pe ti nwọn ba ti ṣi t'Eko tan, nwọn a ṣi tun ṣi ti ilu Kano loni oloni pelu.

Ẹnikẹni ti o ba sun ki o dide, nitoripe ẹ j a le fi ẹja jẹ ninu aiye ti a wa yi, Laisi aniani, Banki Larubawa yi yio [illegible] se ninu ọdun Ileya ati lọdọ awọn Alhaji Ọlọla Amodu Bello, ewo lẹ ṣe o?

## [illegible]ijojo Nsogun

Oi[illegible] ara ogan ko le ni ọrọ Alaiye'uwa Ọba Adem[illegible] Eran-jogun-ọla ti a gbọ wipe ara rẹ se e, [illegible] de si i, ẹtadinladọrun ọdun kiṣe ọmọde ọdun [illegible] fẹ wa wo "Kabiyesi" ni ile iwosan oritameria n[illegible] mo gbọ wipe dokita - agba ti wipe ki nkan ko ṣe ile rẹ [illegible] biyesi" le sinmi daradara.

"Kabiyesi" [illegible] ọdun, ẹ ku iyedun. Lisabi yio jẹki a tun fi oju kan ara ni Ab, Olumọ, Kabiyesi!



Aworan yi n i t i Dokita Maurice Wilkins, igbakeji ọga ilewe giga King's College ni London nibiti nwọn gbe ti nṣe iwadi ijinlẹ egbogi o r i s i r i s i fun anfani awọn ara aiye. Dokita Wilkins ati Dokita C r i c k ni nwọn jọ gba ẹbun iyebiye kan lori iwadi egbogi laipe yi.


## LAGOS RACE CLUB

CHRISTMAS MEETING 1962/63.

SATURDAY 22ND, WEDNESDAY 26TH, SATURDAY 29TH DECEMBER, 1962.

TUESDAY 1ST AND SATURDAY 5TH JAN. 1963

Racing Starts at 3.00 p.m. each day of the Meeting.

DECLARATION.

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30 p.m. and 2 p.m. on Racing Days.

ADMISSION: 3/- PER DAY.

Including Entertainment Tax.

CHILDREN

No Children under the age of 14 years will be permitted [illegible] the Members Enclosure.

SWEEPSTAKE.

On each day's race meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10.0d; 2nd £1.10/- and 3rd 10/-.

# Nwon Yinbon Pa Omo Ilewe Kan

ENUGU - Awọn ọlọpa ilu Ẹnugu nwa awọn ti o yinoọn pa ọmọ ilewe kan ti oruko rẹ nje James Nweke ni ileto kan ti o nje Amaeke Alayi, ni agbegbe Bende.

Irohin ti a gbọ ni wipe awọn ẹgbẹ rẹ meji kan, awọn Francis Okereke ati Pius Ukanku ni o wa ninu iyara lọdọ ọmọ ilewe yi nigbati nwọn fi yin ibọn na pa a. Ibọn a-fọwọ-da ni nwọn fi pa a. Awọn ọlọpa si ti ni ki awọn ọrẹ rẹ mejeji wa sọ tẹnu wọn nipa ti ọrẹ wọn ti o ku na.




# Ayara Bi Asa

Tani o sọ wipe enia-dudu ko le ba awọn Oyinbo alawọ funfun fi agagba sa ninu agbara ere sise ? A ko sọ ti nkan ogun jija o, ki oluwarẹ sọ wipe on ko sọ bẹẹ mo nitoripe arun oju ni ọrọ na nis si yi.

Ninu aworan meji ti o wa'loke yi ni ẹ o ti Ọgbẹni S. Antao, ọmọ ilu Kenya ti o wa larin awọn enia mẹta kan ti nwọn sare nibiti gbogbo agbaiye wa ṣe ere laipẹ yi ni ilu Anstralia. Antao yi ni o gba ipo ikinni, ẹnikeji ni o wa ni apa osi orukọ rẹ si njẹ Tom Robinson ara ilu Bahamas pẹlu G. Holdsworth ọmọ ilu Australia ti o gba ipo kẹta.

# E ka

## Iwe Irohin Eleti–Ofe Ti O kun Fun Irohin Aladun.

# Itan Ajapa Ati Ojola

(O bẹrẹ loj·· ewe kẹta)

**Enia Toto**

Nigbati ajapa pada de ile, on na wa bẹrẹsi ro nkan ti on yio ṣe ti Ojola paapa yio fi mọ wipe on ko fẹ ki on Ojola ba jẹ onjẹ mọ. O wa lọ ra igbokun o... m ọ r a rẹ yi awo-onjẹ tirẹ ka.

Bi nwọn ti ṣe onjẹ tirẹ tan ni on na ti fi igbokun ... rẹ yi awo onjẹ rẹ ka. O wa ni ki ojola wa jẹun. B... a ti de ibẹ on na wa ri wipe ọrẹ on ti ja'gbọn on. Bi ... lọ si idi awo-onjẹ ni o ntẹ igbokun ti ajapa so mọ... molẹ. Ajapa paapa ni ojola, "mo pe ọ wa jẹun ... ntẹ mi molẹ."

Ojola wa pe ọrẹ rẹ ajapa, o bi lere p e tani kọọ ... bayi. Ajapa si daa lohun wipe. "Ọrẹ m i, enia ... kọ ni pe ki a gọ enia na ni nkọ ni ki a gbọn. Itan na kọ ni wipe bi o t wu ki a ma rẹ enia jẹ to, lọjọ kan ni oluwarẹ, a gbọn mọ wa lọwọ.

**YOU WILL NEVER GO WRONG**

When you select and buy any of the following :-

100 o/o WOOL FANCY WORSTED SUITINGS
(Made in England)
(guaranteed against SUN, AIR & RAIN)

BEST QUALITY GERMAN VELVET
(Various attractive designs & colours)
unbeatable quality & design.

HEAVY COTTON GUIPURE ALLOVER
(LACE)

HIGH QUALITY FANCY FURNISHING MATERIALS
(In Art Silk) various design & colours
Price to suit all pockets

HEAVY ART SILK BROCADE
in various colours

(OKUNOWO SPECIAL DESIGN)

**ONLY FROM**

**THE HOUSE QUALITY & DURABILITY**

**OKUNOWO BROTHERS**

63, Massey Street, Faji, Lagos.
Telephone: 23114.

# C. I. D. Man Gets Experience With British Police

LONDON — A six-week training course in the finger-print department of a British constabulary head-quarters has given a Nigerian detective his first opportunity to use his knowledge at the scene of a real crime.

He is Constable Anthony Ibeneme, of C.I.D. Head-quarters, Lagos, who has been working with British police experts on crime investigation in the towns in the West Riding of York-shire.

"They gave me every chance to gain valuable practical experiance in examining for fingerprints some stolen cars and burgled premises. The amount of skill that goes into their work is fascinating," he told an L. P. S. correspondent yesterday.

Mr. Ibeneme, whose home is at Ogbelulu, Orlu District, Eastern Nigeria has been taking a course at the Wakefield headquaters of the Yorkshire Constabulary.

"The course has covered more advanced work than I have done before and the experience will be of great value to me when I go home," he said.


RECORDS OF THE WEEK

78 RPM at 7/– each
P.82527H
Orin TunTun Tide/Kinikan Nseru Bami S. Arowereyin & His Group
P.82504 H
Toba Iowo Mayo Layoju/ Oluwa Loluso Agutan
Federal Rhythm Brothers
P.82528 H
Olo Mi Atata/Abiodun Onibokun C. A. Balogun and His Abalabi Orchestra Ilesha
45 RPM at 6/9d each
P.382447 F
Ko Forun/Papingo Davalaya
Victor Olaiya & His 'All Stars'
P.382462 F
Otan Bebrebeyi/Me Begyaa Mo
E.K'S Band.

PHILIPS
of course...
—the records of the century—
Philips (Nigeria) Ltd.,
Head Office: P.M.B. 1136
Apapa.
Branch Office, P.O. Box 429
Enugu


## Nigerian Piiot Qualifies In England

Perth-A cross-country flight over snow-covered ground in Britain has won a commercial pilot's licence for a young Nigerian who is training to become an airline pilot with Airwork Services Training Ltd. at Perth aerodrome, Scotland.

He is 23-year-old Frank A. E. Osakwe of Onitsha, Eastern Nigeria who began training at the Perth Flying School in November, 1961 and hopes to join Nigeria Airways early in the new year after taking his instrument rating examinations.

"The training at Perth is very sound, said Mr Osakwa. "There is everything that any trainee could want and the instructors are all first–class pilots who take a genuine interest in their pupils."

Frank is one of an annual quota of Nigerians taken for training at Perth to provide both pilots and ground engnners for Nigeria Airlines. Airwork Services have trained some 40,000 air and ground crews from all over the world sinceit was founded about 30 years ago.

## FLYING FOOTBALLERS!



The goalkeeper won this jumping duel during an English second division football match between Grimsby Town and Charlton at the latter's Valley Stadium in London recently.

Here goalkeeper Wakeham is head and shoulders above Grimsby's centre-forward McLean and his own defenders, to tip the ball safely away from the goal-mouth.

## Ejo Anotu
( O bẹrẹ loju ewe kinni )

Apatira, iya Alhadji na gbe e wá fẹ ni ati pe baba on lo si fun u ni ile na rara Alhadji Gbadamosi si sọ pe rara. Alhadji Gbadamosi si sọ pe ọmọ rẹ ni on n ṣe Obinrin na ni on ọ ko ẹru si K ẹ i ṣ e ile Alhadji Gbadamosi

Lọya M. K. Gbajabiamila ni i agbejọro obinrin na. Lọya Harrison Ọbafẹmi si ni i agbẹjọro Alhadji Gbadamosi paapa.

## Ina Jo Ilewe Giga Igbobi

YABA — Ni owurọ ijeta ni awọn ọmọ ile iwe giga ti Igbobi fẹ ṣe aṣẹyẹ "a kawe-pari" ni ina nla kan jo gbọngan ile iwe wọn ti nwọn ma npejọ si na kanle patapata, gbogbo nkan ti ina na baje lẹ ni ẹgbafa pọnun, (£12,000).

Ko si ẹniti o le sọ irohin bi ina na tiṣe bẹrẹ sugbọn o ti jo ọpọlọpọ ẹru bi duru awọn ọmọ ile iwe na nlo pẹlu awọn aworan Olowo iyebiye ti nwọn fi kọ ara ogiri, ki ọkunrin ti o nṣọ ile iwe na to fura pe ina njo.

Ina miran ti o tun jo ni arin ọsẹ yi ni eyi ti o ṣe wọn lofo ni eyiti o ṣẹlẹ ni Mushin lowurọ jẹrin ninu ilu Alufa kan S. Bakare ni oju-titi Masalasi lọ kiri ni Asabaa. Ki o to pada de gbogbo ẹru iyara rẹ ati tira pẹlu we alukurani a ti jona ra apata.

## Oloye Ojikutu

(O bẹrẹ loju ewe keji.)

"Oloye A. Y. Ojikutu ni i gbogbo awọn ti a daruko nwọnyi ati ṣuke wọn ko ṣe ẹhin lakureghe ni ọrọ wọn jẹ lọdọ on Oloye Balogun ilu Eko ti tun ṣe Olori gbogbo ẹgbẹ Alapata Eko.

Sugbọn gẹgẹbi mo ti ṣe alaye fun ẹnyin ti ẹ nka ọrọ idi abajọ ede aiyede ẹgbẹ Alapata Eko, ṣe ẹ wa ri gbangba nisisiyi pe emi baba ẹgbẹ wọn ni o sọ aiye ọpọlọpọ dẹrọ, a fi alaimọre, afibisuolere enia lo le fọwọ s'ọya ninu gbogbo wọn wipe nko ṣe ire kakan fun on, oko ẹru ni mo fẹ 'o awọn lọ.

Ọrọ re o ẹnyin ara wa e ku ipalẹmọ ọdun.

Union Printing and Publishing Company 28 Kosoko St Lagos Box 467 Phone 2333 Editor(Olotu) Ọla Onatade 15 Kosoko St Lagos.



The load is heavy, the ground difficult, the engine is working at full power and yet the driver has perfect control. The light Mercedes-Benz recirculating ball steering is precise to a fraction of an inch. Exact manoeuvering, safe use of marginal space, absolute track steadiness and excellent lock are features of this steering which is just one of the many advantages that all Mercedes-Benz trucks and buses have in common.

**Precision to a fraction of an inch**

MERCEDES-BENZ



Available at

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA.

Sub—Distributors:

# ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.